# Ǹjẹ́ Ó Dàbí Ẹni Pé…

## A dá ọ dá ara rẹ bí?

## O kò ní ìdánilójú nípa àwọn ẹtọ́ rẹ lẹ́nu iṣẹ́?

## Ìwọ nílò ìrànlọ́wọ́ láti kọ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì bí?

## Usdaw lè ràn ọ́ lọ́wọ́ – àwa ní àjọ àwọn òṣìṣẹ́ rẹ.

## Iye owó àjọdá

Iye owó àjọdá fún jíjẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ Usdaw jẹ́ ọ̀kan lára èyí tó kéré jùlọ láàárín àwọn oríṣiríṣi àjọ òṣìṣẹ́, a sì má a fún ni ní àwọn àǹfàní àti àwọn ìpèsè mímọ̀ọ́se aláìlẹ́gbẹ́ fún iye owó tí kò tó ǹǹkan lóòjọ́.

## Fún àlàyé síwájú síi tàbí láti darapọ̀ mọ́ Usdaw:

- Kàn sí aṣojú Usdaw rẹ
- Kàn sí ilé-iṣẹ́ Usdaw agbègbè rẹ
  **0800 030 80 30**
- Kàn sí àyè wa lórí ayélujára
  **www.usdaw.org.uk**

Àlàyé tó wà nínú ìwé pélébé yìí jẹ́ èyí tó tọ́ ní ọjọ́ tí a tẹ̀ ẹ́ jáde – Oṣù Keje, Ọdún 2017.

Usdaw
Union of Shop, Distributive and Allied Workers

Akéde tó ṣe àgbéjáde yìí ni Usdaw
188 Wilmslow Road
Manchester M14 6LJ

Ìdí mẹ́fà pàtàkì tí o ṣe gbọ́dọ̀ darapọ̀ mọ́ Usdaw – àjọ àwọn òṣìṣẹ́ rẹ.

Yoruba

# Ìdí mẹ́fà pàtàkì tí o ṣe gbọ́dọ̀ darapọ̀ mọ́ Usdaw...

1. A mà a ńran àwọn ọmọ ẹgbẹ́ wa lọ́wọ́ láti ṣe ìwádìí ẹ̀tọ́ wọn lẹ́nu iṣẹ́. Bí àpẹẹrẹ, ǹjẹ́ ìwọ mọ̀ pé o ní ẹ̀tọ́ sí:

   – Ibití iye owó iṣẹ́ gbọ́dọ̀ kéré dé fún àgbàlagbà òṣìṣẹ́. Èyí a má a lọ sókè síi lọ́dọọdún, bẹ́ẹ̀ sì ni láti ọjọ́ kìíní, oṣù Kẹrin, ọdún 2017, iye náà jẹ́:

   £7.50 fún wákàtí kọ̀ọ̀kan fún ẹni ọdún 25 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ
   £7.05 fún wákàtí kọ̀ọ̀kan fún ẹni ọdún 21-24
   £5.60 fún wákàtí kọ̀ọ̀kan fún ẹni ọdún 18-20
   £4.05 fún wákàtí kọ̀ọ̀kan fún ẹni ọdún 16-17

   – Ìsinmi ọlọ́jọ́ 28 tí a sanwó fún lọ́dọọdún (fún ẹni tí ńṣiṣẹ́ ọjọ́ 5 láàárìn ọ̀sẹ̀ kan).

   – Ìsinmi wákàtí 11 lójoojúmọ́.

   – Ọ̀pọ̀lọpọ̀ òṣìṣẹ́ ló ní ẹ̀tọ́ sí owó ìtọ́jú ara ẹni nígbà àìsàn lẹ́yìn àìsàn tó kọjá ọjọ́ mẹta.

2. Àwa a má a dá sí wàhálà tó bá kojú àwọn ọmọ ẹgbẹ́ wa lọ́dọ̀ àwọn olùṣàkóso iṣẹ́, a sì má a ńṣojú fún ọ nígbàtí o bá ṣẹ̀, tí a sì pè ọ́ láti wá sọ ti ẹnu rẹ.

3. A má a ńfún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ wa ní ìmọ̀ràn Ọ̀FẸ́ lábẹ́ òfin, a sì má a ńṣojú wọn bí ìjàmbá bá wáyé lẹ́nu iṣẹ́, bí a bá dá wọn dúró lọ́nà àìtọ́, àti bí a kò bá ṣe ohun tí ó yẹ fún wọn.

4. A lè ran àwọn ọmọ ẹgbẹ́ wa lọ́wọ́ láti ní àǹfàní sí ìkẹ́ẹ̀kọ́ Ọ̀FẸ́ nípa àwọn oríṣiríṣi àkórí bíi èdè Gẹ̀ẹ́sì, Ìṣirò, àti ìmọ̀ nípa ẹ̀rọ kọmputa.

5. Àwa a má a ṣe ìpolongo lòdì sí ìyanisọ́tọ̀ àìtọ́ nítorí ẹ̀yà ẹni, a sì má a ngbé ìṣesí tó dọ́gba lárugẹ fún gbogbo òṣìṣẹ́.

6. Àwa a má a ṣiṣẹ́ láti mú ìlọsíwájú bá iye owó iṣẹ́ àwọn òṣìṣẹ́ wa, àti ìgbésí-ayé wọn lẹ́nu iṣẹ́.

- Gbogbo ènìyàn ni ó lè darapọ̀ mọ́ àjọ àwọn òṣìṣẹ́.
- Ìwọ ní ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin láti darapọ̀ mọ́ àjọ àwọn òṣìṣẹ́.
- Ìwọ kò nílò láti sọ fún agbanisíṣẹ́ rẹ pé o jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ àjọ àwọn òṣìṣẹ́ kan.
- Ó jẹ́ ohun tó lòdì sí òfin fún ẹnikẹ́ni láti hùwà sí ọ́ lọ́nà àìtọ́ nítorí tí o jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ àjọ òṣìṣẹ́.